Ìpinu Egbé Ònkòwe PEN Ni Québec Lori Isé Gbédègbeyò Fún Àwon Tí N Kòwé

1. Isé onà àtokànwá ni gbédègbeyò jé. Ó jé ònà kan pàtàkì tíí mú ìlosíwájú bá iyì tó wà nínú àìsètàn, wíwà 'lálàáfíà àti ìròrùn. A máa tako ìyànje, èké, jíjegàba àti ànìkànjopón. Isé gbédègbeyò gbé ìgbóraeniyé láruge.

2. Gbogbo òlàjú kó ló rí bákan náà ní ìhà tí wón ko sí isé gbédègbeyò fún ìwé àti àwon ònkòwé. Àwon òlàjú míràn a máa se gbédègbeyò torí ó wù wón, àwon míràn ní torí ó kanpá. Isé gbédègbeyò se pàtàkì nínú ìgbéláruge èdè àti òlàjú.

3. Pèlú òwò fún àwon ònkòwé àti ìwé tí wón ko, àwon gbédègbeyò náà jé ònkòwé aláròfò láàyè ara tiwon. Won a máa lo opolo won fún ìtumò isé ònkòwé sí èdè míràn àti ìlosíwájú isé ònkòwé láti tan isé náà kárí ayé. Gbédègbeyò kìí se eni afisérán nìkan; bí o tilè jé pé wón n gbé ìtumò láti èdè kan sí òmíràn ni, àwon pàápàá ní ohùn ara tiwon. Ní pàtàkì, won a máa wá bí òlàjú orísirísi se leè fesèrinlè nípa dídúró ti àwon ònkòwé, ewá ìwé kìko àti àwon ènìyàn pàtàkì tí ayé kò tîì fi béè dámò.

4. A kò gbodò fi ètó àwon gbédègbeyò dù wón. Àti ìjoba àti atèwe àti olùfonrere àti agbanisísé - wón gbodò bu iyì fun isé gbédègbeyò láwùjo, kí wón sì pòkìkí orúko won, kí oun àjemónú kún ojù òsùwòn ní ibi yoowù tí won ti n sisé.

5. A kò gbodò dún mòhuru mo àwon gbédègbeyò nígbà kóòkan torí isé won.

6. Gégé bí ònkòwé aláròfò ní owó ara won, pèlú ìmò àti làákàyè tó jinlè, a gbodò bu olá fun gbédègbeyò kí a sì bèèrè oun tó bá rú ni lójú nínú isé won lówó àwon pàá. Gbédègbeyò ló ni isé tí won bá se.